Draft Summary to the Government

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. NO. 284 SATURDAY, JULY 21, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.


## *White's Radical Gonkiller.*

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

NIGERIAN SECRETARIAT 1 AUG 1928

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

**N.B.**—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.


Akinṣuyi


SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
Medicine Dealers
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
Ulcerated Teeth
Stiffness and Soreness after Severe Exercise
General Directions for External Use
LOOK FOR THE PORTRAIT OF
D. Earl Sloan
TO STOP
YOUR ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale: Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd. London Eng.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RE.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okerẹ. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### KINLA ? OKU DI MEJI !

Irohin kan ni nilọlọyi pe bi ọkọnrin kan ti gbe oku ru lati lọ sin ni apa ilu keji bi o si ti ngun afara ti a sọpe o mbẹ ni Odo nla kna kọja bẹni ẹsẹ rẹ tase t on t'oku ti o ru si ṣubu sinu omi ati ogun pọun ti a sọpe ọkọnrin na so mọdi lati lọ fi sinku rẹ: Ki ariwo to ta, iṣan lile si ti gbe ọkọnrin yi lọ pẹlupẹlu oku ti o ru raurau: iyoku iregbe nigbehingbẹhin ni a gbọ pe awọn kan ri oku ọkọnrin na, ati oku ti o ru ti nwọn di mọra wọn papa koko.

## DUNIYAN—LABARI.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

### OLOGBE TOM JONES.

A gbọ pe nwon wo ile kan ti ologbe Tom Jones ni Ẹhin-Ọgba lati ọjọ Friday to kọja na, eyiti a ngbọ wipe ologbe na lo ṣe iwe-ogun (Wills) silẹ wipe ki nwọn fi ile ti a wi na kọ ile "Hall") iwe fun gbogbo enia, ti awọn Baba-nsiku rẹ si fẹ muṣẹ yi.

### OYINBO WALKER.

A gbọ wipe oyinbo Major G. H. Walker D.S.O., olori Ọlọpa Pataki (Deputy Inspector-General of Police Colony) ba ọkọ "Aba) ti o ṣi nihin ni Jimọ tokọla lọ si ilu Oyinbo.

### PANTIWA?

Rogbodiyan kan li a gbọ larin ọsẹ to kọja pe o ṣẹlẹ larin Alaji Saka pẹlu awọn kan ni Mọṣalaṣi-Jimọ (The Central Mosque) larin ọsẹ to kọja; a gbọ wipe akitiyan na di ogun ọran ile ẹjọ.

### ỌKỌ "OSHOGBO"

A gbọ wipe ọkọ yi ti nṣe ti awọn oyinbo Ọlọkọ Elder Dempster & Co.) bajẹ lọna irin ati lẹnu iṣẹ rẹ lati ọna ilu Port Har Court, ni arin ọsẹ to kọja, eyiti a gbọ wipe nwọn ran ọkọ kan to njẹ "Attendant" lọ fun lati ṣe igbala jamba to ṣẹlẹ na, a si gbọ wipe ọkọ na ti pada de sihin, eyiti a gbọ wipe ọkunrin Aganyin kan ṣiṣẹ ti o jọju fun gbigba ẹmi awọn enia ti o mbẹ ninu ọkọ la, ti nwọn si ta ọkunrin na lọrẹ, bi eyi ba jẹ bẹ, a yin awọn Ọlọkọ na tun irutẹ itara ti nwọn ni si ewu ti o wu awọn ẹniti o mbẹ ninu ọkọ na, ki Ọlọrun fi mọ bẹ o.

### ỌGAGUN RUXTON.

Agbo pe Ọlọla Major U. F. Ruxton, C.M.G., Lieutenant-Governor dakan lọ si idalẹ ninu ọsẹ to kọja yi, eyiti a si tanma pe ki yio pẹ ki o to pada.

### ADAJỌ AGBA.

A gbọ wipe Onidajọ Agba Sir Ralph Combe lọ si ọna ilu oke ni ọjọ Alaruba to kọja lọhun fun ẹjọ Ganran ti Ibadan.

### KINLA ! EMI NU?

Nwọn gbe kini kan si ikorita-mẹta Oke Arin leti ibusọ awọn Onilẹkẹ larin ọsẹ to kọja. A ri igba kan a si tun ri egbinrin aṣọ funfun kan, ṣugbọn ki o to di ọjọ keji a ti fẹ igba na ku, kinla! Ẹbọ tabi kini nyẹn ?

### O D'OJU Ẹ!

Gbagbagba ni Ọpa-Ọba kan nyan lọ ka nyan bọ ni ori pepele Mọṣalaṣi-Jimọ (The Central Mosque) lati arin ọsẹ to kọja yi: Aja lo lẹru gan!

### BARIKA O.

Ọlọla Gomina Graeme Thomson G.C.M.G., K.C.B, de ni ọjọ ọsẹ ijeje lati irin ajo rẹ (Kamaru) ti o tilọ lati ọjọ kẹsan oṣu June to kọja yi—Ẹ ki abọ o, alafia kọ ni ẹ de bi ?

### ỌṢỌ STREET.

Adugbo yi ko wọ arara fun iru ipo ti o wa gẹgẹbi o ti jẹ wipe omi ti o mu pẹtẹpẹtẹ wa mbẹ ni apakan Adugbo na papa lẹnu ọna ile ẹlomiran ni eyiti a ri wipe ko le fun wọn ni ilera tabi alafia; nitorina a ke si awọn "Lagos Town Council" ki nwọn fi oju si adugbo na fun ilera ilu.

### MACAULAY PẸLU IBERE GBANGBA.

Ọgbẹni Macaulay ọkunrin na tun de o, gẹgẹbi o ti kọ iwe lọjọ kini sinu iwe-irohin "Weekly

Record" ti ọjọ 13 oṣu June 1925, pe on fi Ọlọrun lẹ Ijọba ki nwọn wadi rudurudu ti o wa Ile Ọbalẹ Ijọba ki nwọn wadi rudurudu ti o wa Ile Ọba-Dosunmu larin on Macaulay, Carr ati Oloye Ọbanikoro (Adamọ Akẹju) ti Ijọba ko si le ṣe bẹ titi ọjọ owuro yi, a tun gbọ ọrọ na ninu iwe-ojojumọ (Daily News) ti Monday ọjọ 16 oṣu yi, eyi fi nhan wa wipe ọkunrin na si wa lori ọran rẹ na: Ewo lewo?

## EGUNGUN IDUNGANRAN MA YE KO GBA ESUGBAYI LOWỌ AWỌN ORẸ DABẸ—NYANKỌ RẸ!

Bi iwe wa ti nlọ si otẹ lọsẹ to kọja li a gbọ wipe nwọn nlọ si Kotu lati 10jo ti nwọn fi erukọ Eṣugbayi pe awọn olori Ọlọpa ti dudu ti funfun ti o mu lọ ni ọjọ kẹjọ oṣu Ọgọsti, nwọn pe oni Motọ lẹjọ pẹlu. Ẹnyin enia wa eyi ṣẹ di ọwọ agbere patapata ninu aṣeju nigbati ofin Ogbe-fohun-folohun ti nwọn npe ni Habeas Kopọs ko lọ awọn Alaṣẹ ilu awọn iranṣẹ li o ma wa lo. Eyi kọ li a npe ni o fi onija silẹ gba alapẹpẹ loju? Ẹru ti o mba awa ni pe ki awọn ti o nṣe eyi ma jẹ pe nwọn nṣe Eṣugbayi li aṣepa patapata ni. Bi a le ni, bi a ko ba ni, a ki dẹhin lẹhin ẹni. A nwi tiwa to! nitori nigbati a ba tun ma gbọ ohun ti Ijọba ma ṣe fun Eṣugbayi nidi ẹjọ ti o tun pe yi ki a ma lọbosi o! A ko mai ti ri ẹni ja wa niyan pe nwọn din owo rẹ si pọnwun marun?—*The African Messenger 31/12/1925.*

---

## IROHIN IJẸBU RẸMỌ, LATI ỌWỌ J. A. O. SHOMADE.

Mo fi towọtọwọ ati itẹriba a tọrọ adura fun awọn ọmọ Ile Ẹkọ ti wọn ti nṣiṣẹ ati awọn ti ko iti jade Ile Ẹkọ pẹlu ti wọn ti di ẹni pataki ninu Ẹkọ ti ao si mọ gẹgẹ bi Iku tiṣe mu wọn lọ larin awọn obi ati ni idalẹ, bo ba tilẹ jẹ ẹṣẹ ni ki Ọlọrun jọwọ dari ẹṣẹ na jinwa. Bi o ba dẹ tun jẹ idanwo ni ki Ọlọrun jọwọ ba wa dawọ idanwo na duro. Bi o ba dẹ tun jẹ ọwọ awọn enia buburu ni o, ki Ọlọrun jọwọ ba wa tu ọna aṣiri wọn ki o ba wa dojuti wọn Amin.

Ọlanipẹkun ọmọ Akarigbo ọlọla nla ọmọ Mr. D. A. Joshua, ọmọ Mr. Aṣẹlesi, J. A. Ojuile ko jọ ti ẹgi oko ọlọla, ọmọ Mr. Oduẹsọ, abẹ awọn Ijọ Catholic mimọ ninu ọla wọn, abẹ awọn Ijọ C. M. S., ninu ọla wọn, abẹ Ijọ awọn Wesleyan mimọ ninu ọla wọn, abẹ awọn Ijọ Ibamitis mimọ ninu ọla wọn, abẹ awọn Ijọ Ẹgbẹ ọmọ ogun Kristi nipa iwosan amodi nipa adura, abẹ awọn Ijọ Sarahfim ninu ọla wọn, abẹ gbogbo awọn Ijọ Afa Imale ti o ni ẹmi mimọ Ọlọrun ni ọkan mimọ ninu ọla ti wọn, abẹ gbogbo awọn Ijọ enia dudu Ọlọla nla ni ọla wọn fun adura yi. Ki Ọlọrun fi oju (Anu) Anu rẹ wo gbogbo wa Amin.

Ko si jọwọ ko da iku awọn ọdọmọde dum... wa nitori owe enia dudu ni yi pe Ogede ku ... ọmọ rẹ rọpo. Ina ku o fi eru boju Ki Ọlọrun Oluwa Olodumare jọwọ ba wa tu Iya ati ... wọn ninu, Amin. Ki Ọlọrun Oluwa Olodumare jọwọ ma jẹ ka tun ri iru rẹ ni arin gbogbo ... Rẹmọ ati nilẹ gbogbo Ijẹbu, ati ni ilẹ gbogbo agba-aiye Amin.

Ki Ọlọrun Oluwa Olodumare jọwọ ba wa ... ilẹkun buburu ki Ọlọrun Oluwa Olodumare jọwọ ṣi ilẹkun rere fun gbogbo wa Amin. Ki Ọlọrun Oluwa jọwọ bo aṣiri gbogbo wa di alẹ ni ile aiye ati ni ọrun Amin.

J. A. O. SHOMADE.

---

## ANKURI MAGANI DUNIA.

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Ọrọ ti o mbẹ loke yi, itumọ rẹ ni wipe suru ni ogun aiye lede awọn Hausa.

Nipa eyi a fẹ ki gbogbo wa mọ wipe ohun ti suru ba ṣe ti, nkan na ku sọdọ Ọlọrun, nitorina gbogbo ohun ti awa ẹda ba nfẹ lode aiye yi, o nfẹ ọpọlọpọ suru; eyiti a kole ṣẹṣẹ sọ ọpọlọpọ nkan rere ti ẹda ti fi suru ri larin ilu yi ati nibomiran, bi o ti wu ki o ri a o ma fi iṣẹ ti suru ma nṣe han nyin lẹkankan, papa lori itan kekere kan to wa si ẹnu wa loni yi, eyiti o fi han wa ti o si kọ ni nipa iṣẹ suru, ti a si nfẹ ki ẹnikẹni ma fi si iranti wipe ti enia ba nwa ohunkohun pẹlu suru bi o ti wu ki o pẹ to suru na li yio fi ṣẹgun tabi li yio fi ri ohun na ni iwọn igba ti ko tanma.

Itan wa na dori ko dori, o dori ọmọ onile kan ati ọmọ ajeji kan ni arin ilu kan. Itan lọ bayi pe ibinu ko da nkan suru baba ireti on lo difa ojọ kan fun ọmọ onile yi ti o nṣawo lọ si ile-iwo, ani ki o rubọ ija o gbọ o ru u, ile-iwo san u.

Ọmọ onile ti a wi yi gbogbo aiye lo nfẹ ẹ, bi ẹni owo: Baba ti o bi ọmọ onile yi ti jẹ Ọba ri ni-gbati baba na waja eyiti a mọ ni (ipapoda) o sọ fun awọn ti o mbẹ pẹlu rẹ po ti on ba papoda, arọmọdọmọ on li ki o ma gun ori alefa on gẹgẹbi okiki orukọ ohun ti o ka arin gbogbo ilu na, adehun na duro bi "I" gbogbo enia si gba fun u.

Lẹhin eyi ọkan ninu ọmọ rẹ gun ori Alefa rẹ, ko pẹ lẹhin eyi jọjọ ti eyiti a wi yi waja gẹgẹbi ipo baba wọn, atẹle keji tun gun ori Alefa yi kanna, lẹhin ti ọpọlọpọ ọpẹ alaiye mbẹ nigbati eyiti a wi ṣaju waja ti a si nfẹ fi omirau ro'lẹ lori rogbodiyan na ni ọmọ baba ti o giriki yi de ni nwọn si fi si

ori Alefa baba wọn ti a wi na, tẹmbẹlẹkun pọ jọjọ sibẹsibẹ ọmọ onile ti nwọn fẹ ko ba wọn ṣe akatakiti kan pe dan-dan itẹ baba on ni ki nwọn jẹki on wa nibẹ tulasi, nitori ẹla lọrọ!

Lẹhin ti gbogbo ritiriti ọran na rẹ'lẹ ti ilu ṣe gẹgẹbi adehun ọba ti a wi na—ọmọ onile na mba ọba yi bọ titi, ki a ri ki a fọ, a ri ọkan ninu awọn ẹmẹwa ọmọ onile na eyiti o dide ti o si bẹrẹsi ditẹ si i, gbogbo jakanjankan ni ko wu tẹlẹtẹlẹ pe ki nwọn yan ọkan ninu ẹmẹwa ti a wi gẹgẹbi isangbe rẹ, nitori iwa jagidijagan rẹ, ṣugbọn ọkan ninu awọn ọrẹ isangbe na lo dide si ori ọran na pẹlu ọpọlọpọ wahala ki o to le jẹ isangbe ọmọ onile na, ti ọmọ onile na si gba fun wọn, ṣugbọn lẹhin na kọ lo tun wa di ẹniti o ngbọtẹ si ọmọ onile pada, iru rẹ ka'iye ọmọ-ajalọrun.

Larin igba ti ọkan ninu isangbe ti a wi na nṣe igbọtẹ si ọmọ onile, li awọn ẹnu-mi-tolẹ bẹrẹ si ko'ko-ro fun u ani gẹgẹ bi iwa ọtẹ ati iwa abosi rẹ, nigbati awọn ara ilu karikari tun bọ ri wipe isangbe lasan na tunbọ ntẹramọ iwa buburu rẹ ati iwa arakan si awọn ẹlẹgbẹ rẹ iyoku dede, ilu kọ ẹhin si i, larin akitiyan na ni ọmọ ajeji kan ti a darukọ ṣiwaju yọju wurẹ ti o si fa ẹmẹwa ẹkan bọdi pe ki o ba on rin'rin bi on tiṣe le gba Alefa baba ọmọ onile, nitori o tilẹ wu on pupọ on si ti nwa alefa na lati gun tipẹ jọjọ, ẹwẹ on si fẹ ya oro, ki a ma dalọ wọnna, ọmọ ajeji yi bẹrẹsi gbọn owo danu, tobẹ ti gbogbo ohun alumọni rẹ fẹrẹ tan si i, sibẹsibẹ ko kọ o tunbọ nu 'ri mọ tantan—iyẹn ni wipe o nfẹ jogun buruku, ẹwẹ o si nfẹ ko ararẹ sinu fitinati aiye.

Ki a ma fa ọrọ gun lọ titi nitori itan pọ nibẹ ati pẹlu a ge ọrọ na si ku-ku-ku ni ki o ma bo rẹ nyin lati gbọ, nitori ti a ba ni ki a ma sọ itan na lọ gbọrọ lọdun meji loni a ṣi wa lẹnu rẹ.

Nigbati ọran da bayi ilu ni hẹn kinla! ewọ ni ti igi ọwọ, ṣugbọn ẹmẹwa ti a wi nyẹn nsọ fun ọmọ ajeji na wipe ki o ma da wọn lohun iyẹ ẹiyẹ ki i wọ ẹiyẹ lọrun, ko wa mọ wipe bi iyẹ ẹiyẹ ba bọ sinu epo yio wa lẹsẹ ti yoi fi fo pẹlu nipa bẹ awọn ara ilu na da si meji gẹgẹ bi o ti jẹ wipe awọn ojulumọ diẹ ti mbẹ lẹhin ẹmẹwa kan yẹn nigbati ọran de'lẹ, eyi mu wọn so panpa si arawọn, ṣugbọn awọn ẹniti o mbẹ ni atilẹhin fun ọmọ onile pe kọ si kuku lagbara Edumare jẹ igi lẹhin ọgba ti nwọn si jẹ giriki eyi ti a fẹrẹ le sọ wipe gbogbo enia fẹrẹ tan si ẹhiu rẹ bikoṣe awọn gaga ọwọ melo kan, ti nwọn si dabi alatilẹhin fun ọmọ ajeji na pe ki ọwọ rẹ le tẹ ohun ti o nfẹ, nigbati iyọnu ọran yi papọju (gẹgẹbi adanwo) ọmọ onile yi sọ fun awọn alatilẹhin rẹ pe ki nwọn jẹki nre ile-iwo, ki on gba atẹgun diẹ kiun lọ, ṣugbọn on ko ni tun ṣai pada bọ lọjọ ti ko pẹ, ko tẹ awọn alafẹhinti rẹ lọrun.

Babalawo kan mbẹ ni arin ilu na orukọ rẹ a ma jẹ Ọkanṣọṣọ Ajanaku ti nmi 'gbo kiji-kiji; Babalawo lo wa fun ọmọ onile na, Ifa rẹ si riran pupọ ju Babalawo ki Babalawo lọ koda ki iṣe Ifa yẹsuyẹsu—itumọ Ifa rẹ ni wipe ohun ti o ba sọ wipe on ri bẹni nkan na ma jẹ, nipa bayi lo ṣe ndifa rẹ fun ọmọ onile na (Adifa bi ẹni wẹ'ju) ni oriki Babalawo na, o dahun wipe on yio tilẹ yẹ Ifa on wo lati gbọ ohun ti ọmọ onile na nfẹ ṣe daradara.

O ki Ifa rẹ lọ ṣaṣa, ti nwọn ma nki, nwọn ri ibinu ko da nkan ankuri magani Dunia—suru ni ogun aiye on lo difa ọjọ kini fun ọmọ onile kan ti o nṣawo re ile-iwo kan, ti ọmọ ajeji kan nfẹ gun ori Alefa baba rẹ, a ni ki ọmọ onile na rubọ ija; eṣu mẹwa ati eku mẹsan ki o le lọ 're ki o si le bọ 're, ọmọ onile gbọ o ru u, o palẹ rẹ mọ wu-wu-wu o si fori le ile-iwo lai si ija lai si ita gẹgẹbi Ifa ti fọ ko si idagiri ki idagiri kan ti o ṣẹlẹ ararẹ, inu ọmọ ajeji kan nyẹn pẹlu ẹmẹwa kan inu ọmọ onile ndun yungba bi oyin, bi inu wọn ti ndun, bẹni ilu ndamu gbogbo rudurudu tunbo ndagba si, oriṣiriṣi ohun musaba nṣẹlẹ larin ilu, ile njo ole nja, aisan bẹrẹsi ṣe enia ni arin ilu na, iyan owo ati iyan onjẹ wọn.

Ṣugbọn ki ọmọ onile to kuro ni ile lo ti gegun silẹ wipe, ile Labọye nbọ si, adabi bi on ba binu tẹru-tọmọ ani adabi bi on ba ba ọmọ ajejidu ile baba rẹ ni Alefa baba on yio fi rọ ọmọ ajeji na lọrun—ọpa bibẹko ni egun na ri ni ikẹhin, ohun ti oju oku ri ni Sare ko ṣe sọ o jare ẹnikeji.

Itan na gun pupọ ṣugbọn ti a si ranti nisisiyi I a nsọ yi, ṣugbọn ohun ti a fẹ fa jade ninu itan yi ni suru ti o kọ awa ẹda lati ni pupọ fun iwọn igba ti a ba ntọrọ ohunkohun lọwọ Sati, a ni lati fi suru si i, bi a nṣe adura tọrọ ohun lọwọ rẹ, ki a maṣe sọ wipe ohun ti a nfẹ na ko tẹ wa lọwọ tabi adura mi ko gba ni, ko yẹ ki a ni erokero si irufẹ ọna bẹ, suru ni ki a fi si ni igbati a ko ni ireti ni nkan na ma tẹ oluwarẹ lọwọ, lọna keji eyi ni awọn Yoruba a-kewu ma fa nasi fi npowe bayi pe: suru ni baba ireti tabi atọrọ ohun gbogbo lọwọ Ọlọrun ki kanju, itumọ rẹ ni wipe ohunkohun ti enia nfẹ lai ni tanma ni nkan na ma de ọwọ oluware, ṣugbọn ki a ma fi ọkan mimọ tọrọ ohun lọwọ Ọlọrun ki a si fi suru si i pẹlu, dajudaju Sati yio dahun, nitori o ngbọ'ran o si nri 'ran pẹlu.

Ọmọ onile yi fi suru ọjọ kini ṣẹgun awọn ọta rẹ ti o mba ṣe kokowa latari ogun rẹ. gẹgẹ bi Ifa ti Babalawo "Ọkanṣọṣọ Ajanaku" da fun u lọjọ kini; bi suru nṣe nkan, bi ki nṣe nkan, ẹ ko mọ lọjọ ti ko pẹ yi—Ẹ jẹ ki a ran nyin leti orin waka kan ti awọn Imale ma nkọ, kini nwọn ti nkọ orin na? nwọn ni bi a ba foju kan Anabi awa yio tiṣe o, awa a ma jo awa a ma yọ ni, jigin-jigin awa o ma yọ ni, bẹni a o ma yọ, *Insha-Allaho*, suru dọwọ nyin o.

## IBOSI ALUBA O, ALADUGBO!

Li atetekọṣe ti Ọlọrun da ọrun on aiye ati awọn ohun gbogbo ti mbẹ ninu rẹ tan, O pe awọn Mọlaika rẹ ati awọn ẹda iyoku jọ, O ni ẹ wa ẹ jẹ ki a da enia ni aworan ara wa; gbogbo wọn ni o da o Sati Ọba Aleke-Ọla.

Nigbati Oluwa ma da enia nkọ, O da Adam—Adamọ ati Efa—Awawu, nwọn jẹ ọkunrin ati obinrin, Adam-Adamọ ni ọkunrin, Efa-Awawu ni obinrin, awọn mejeji dabi oluṣọ arawọn, ṣugbọn ni ikẹhin nwọn di tọkọ-taya, Oluwa ko wọn da si inu ọgba Eden *Alijanah*, o si fun wọn ni aṣẹ pe gbogbo eweko ati oniruru ohun ti o jẹ jijẹ nbẹ ni ki nwọn ma jẹ aiyafi igi kan ṣoṣo ni ko fun wọn tabi yọnda lati jẹ, nwọn npe igi kan ṣoṣo na ni igi imọ ati iye.

Ki a ma dalọ wọnna lẹhin ti a gbọ wipe Abiliṣi ( Satan ) lọ ba ẹiyẹ kan ki o gbe on lọ sinu ọgba *Alijanat* na ẹiyẹ na ni nwọn npe ni agunfọn gẹgẹ bi apitan ti pa a fun wa, nigbati Abilisi wi bẹ fun ẹiyẹ na o kọ o ni kole ṣe bẹ, ṣugbọn on le kọ ọ wipe ki o tọ ejo lọ bayi yio le ṣe bẹ, Bilisi gbo o ṣe bẹ, nigbati o de ọdọ ejo, o bẹ ẹ lọwẹ pe ki o gbe on lọ sinu ọgba Eden *Alijanat* ati pe ki o ja eso ti o mbẹ lori igi imọ ati iye na fun obinrin ti o njẹ Efa-Awawu na.

Ejo ṣe bẹ o mu eso igi na fun u, ( eyiyi ni Awawu ) nigbati o gba eso igi na ti o ju sẹnu, o jẹ o wa ri kedere pe a ṣẹ ninu okunkun ni on ti mbẹ ri, o mu iyoku eso na lọ fun ọko rẹ Adam-Adamọ, iyẹn na gba o jẹ awọn meji wa ri arawọn gedegbe nwọn si mọ wipe awọn mbẹ ni ihoho ọmọ-luwabi ki nwọn to wa lọ ja ewe ọpọtọ eyiti awọn mejeji fi ṣe bantẹ ati pọnpondan, ti nwọn si san u lẹhin ti ọran de bayi tan ani ti oju awọn mejeji la si aiye ti nwọn si mọ wipe nwọn ti kuro ninu okunkun; Oluwa wa kọ si wọn wipe Adamọ, Adamọ, nibo lo wa? O ni mo gbọ ohun rẹ, ẹru si ba mi nitoripe mo wa ni ihoho mo si fi arapamọ nje ki lo ti ṣe mọ wipe o nbẹ ni ihoho? o di wo-mi nwo'lẹ, iwọ ti jẹ ninu eso igi ti Mo palaṣẹ fun nyin? nwọn nti si arawọn, nipa Eyi li Oluwa fi le wọn kuro ninu ọgba *Alijanat*, ti O si gegun fun wọn, egun na lo si mba awọn ọmọ Anabi Adamọ ja titi di oni oloni.

Ggbogbo ẹṣẹ ti awọn ọmọ Anabi Adamọ nda ko ṣẹ lori wọn ni iwọn igbati Baba nla wa ti da ẹṣẹ lọjọ kini, ṣugbọn apẹrẹ ni eyi jẹ, gbogbo ẹnikẹni lati mọ wipe ẹniti o ṣiṣẹ rere ni yio ri rere, ẹniti o si nṣe iṣẹ buburu, buburu rẹ ni yio ri.

Kini a npe ni iṣẹ rere ati iṣẹ buburu ngo la han nyin nisisiyi.

Ibẹru Oluwa ti Adamọ ati Awawu ko ba lọjọ kini li o mu wọn kuro ninu ọgba *Alijanat*: Kini a tiṣe bẹru Oluwa; nigbati Oluwa ran Mose-Musa niṣẹ, o fi ofin mẹwa ranṣẹ si i wipe ki o ka fun awọn ọmọ Anabi Adamọ wipe bọwọ fun baba on iya rẹ, iwọ ko gbọdọ jale, iwọ ko gbọdọ pania, iwọ ko gbọdọ jẹri eke, iwọ ko gbọ ṣe panṣaga tabi agbere. iwọ ko gbọdọ ya wọn ni ele, bẹni iwọ ko gbọdọ ni arankan tabi iwa inunibini si ọmọ ẹnikeji rẹ ati awọn iru iwa gbogbo bawọnni, o ni ẹniti o ba ntẹ awọn ofin wọnyi leti on yio jẹ niya gẹgẹbi iṣẹ rẹ, ougbọn on ki yio ṣe ohun ibi kan fun ẹniti o ba ṣọra nidi ofin wọnyi, ofin ti Ọlọrun ni wọnyi ni apẹrẹ ti aiye pe Ijọba kan so ofin kan wipe awọn ọmọ abẹ wọn ko gbọdọ ru, ẹniti o ba ru dajudaju nwọn ni lati jẹ ẹ niya gẹgẹbi ofin.

Bi Oluwa ti sọ ọro ti awọn ofin Rẹ si awọn ojiṣẹ Rẹ ti nwọn si ṣe ni iwe bẹni awọn Ijọba aiye so ofin tiwọn pẹlu sinu iwe; ngbọ awọn ọmọ Anabi Adamọ ẹṣẹ ti olukuluku nda eṣu kọ li o nti wọn sidi rẹ, gbogbo ofin ti a ka yi li a ri ka gedegbe ninu Bibeli ati Alkurani, eyiti olukuluku wa si ni iwe tirẹ lọwọ ni'le Alfa Imale fi nṣe wasi fun wọn titi. Kiriyo si fi nṣe wasu fun wọn nigbagbogbo.

Oluwa ki gbe Musiba kan tabi Aluba si arin ilu lai ni sababi, kini sababi rẹ? ti o tun ju iwa ẹṣẹ lọ; iwa ẹṣẹ awọn ara ilẹ yi papa to Musiba ati Aluba lọtọ.

Ni igba lailai ti Aluba tabi awọn Musiba ba de si arin ilu, ( bi iru eyi ti o mbẹ fun Eko loni ) awọn Alufa Ṣọṣi ati Mọṣalaṣi nwọn a ma gbadura pe ki Oluwa ṣọ awọn ki o si da ọwọ musiba ati aluba bẹ duro lọna ti ẹsin ati igbagbọ, bẹni awọn Aborisa papa yio si dide pẹlu ti nwọn yio si ṣe etutu lọna tiwọn—Ọlọrun yio si gbọ ẹbẹ wọn yio si gba pẹlu, a ko le ṣẹṣẹ ṣiro iru eyiti a nwi yi ti a ti nri larin ilẹ yi lati ọjọ gbọrọ.

Wayi o, tani ko ṣai ri oye irufẹ aisan ti o mbẹ larin ilẹ yi loni bi o ti nṣe awọn ọmọ Anabi Adamọ ani aisan eyiti awọn Alabojuto Ilera-ilu npe ni arun Ekute, ti o si nran awọn enia nitosi ibiti o ba nja tabi ni ibikibi ti o ba wu u?

Ajakalẹ-arun na bẹrẹ ni adugbo Oko-Awo ninu ọdun 1924, ni iwẹnyi eṣi idunrin, arun jẹ arun ti o nfa otutu dani ti yio si di wiwu bi balọ tabi pẹtẹlẹ si ibiti o ba wu ni ara papa nisakani alawẹ-itan tabi ninu koto abiya; awọn Dokita ti o wa fun awọn Munisba fun arun na ni suna *Bubonic Plague*, ṣugbọn awọn ti o jẹ oloye bi onişegun awọn enia dudu sọ wipe gbogbo rẹ iṣẹ ilẹ-gbona ni, nitori on kanna li o nja lọna ti o ba fẹ, bẹni awọn Alfa Imale npe ni Aganna tabi Aluba, oruko mejeji yi Ajakalẹ-arun kanna lo gbe e ru, ṣugbọn ju gbogbo rẹ iṣẹ olode tabi Ṣọpọnna ni.

Awọn Dokita Munisiba dide Ijọba si nran wọn lọwọ pẹlu lati ki arun na wọ tobẹ ti nwọn paṣẹ wipe ki nwọn ma Korọnti *Quarantine* ibikibi ti arun na ba gbe wọ nitoripe arun na mbẹ ni ara awọn ekute ti o ṣoro jọjọ lati ri kekere rẹ o kere pupọ ju ọmọ ina-igun lọ, ṣugbọn nipa ọna Korọnti

yi, pipa awọn ekute ile gbogbo ati nipa titun ile ṣe fun atẹgun lati ma ri aye wọ inu ile ki yio le fun arun na ni aye lati ri enia gbe ṣe.

ki iṣe ọran-iyan jija fun ẹnikẹni nipa aṣẹ awọn Dọkita Munisiba nitoripe ohun ti nwọn mọ li nwọn nsọ, ṣugbọn latari gbogbo wahala ibojuto bayi, sibẹsibẹ arun na tubọ nda bete di bi a ti nwi yi larin ilu yi.

Ohun ti mo fẹ ki a mọ ni wipe, ki a ma pa awọn Ekute-ile, ki a ma tun gbogbo ile wa ṣe daradara o jẹ ohun ti o tọ Suna fun awọn Olubojuto-ilu.

Ṣugbọn sibẹsibẹ O yẹ ki awọn Munisiba mọ wipe arun ti o ti nja lati bi ọdun kẹrin yi ti o si fi ake kọ ri pe on yio ṣe gudu-gudu meje laduru wahala ti awọn Olubojuto-ilu na tiṣe ti nwọn ti mbẹ lẹnu rẹ di isisiyi, o to o yẹ loju ti awa ki a fi ọran na si iwaju awọn ara ilu lati mọ ọna wo ni nwọn le mu u gba, gẹgẹ bi o ti jẹ wipe ohun a ba jọ wo lo ngun, ọran yi ti di ọran bayi ni a ma nikan ṣe.

Ṣe a sọ ni iṣaju larin ọro yi wipe ti Aluba ba wọ ilu yi awọn ara ilu ni Kiriyo, Imale ati awọn Abọriṣa nwọn a dide lati ṣe etutu *( Propitiation )* lọna olukuluku wọn, dajudaju adura wọn yio si gba fun ọmọ ni ọyan, fi ọyan fun ọmọ ọkanna ni mejeji ti ọmọ ba ti mu'yan ṣe ọran ti buṣe, itumọ rẹ ni wipe bi a ba ti ṣẹju arun-ekute wa ṣe ope ka.

Kini ohun ti o ṣe wa loju su lona ti arun na ngba ba enia ja ni wipe ko gbọ nsusun ẹwẹ ko gbọ sise, a ko si le sọ wipe gbogbo awọn ẹniti o nba ogun arun-ekute na lọ ko kuku dẹṣẹ ti o si wiwo jọjọ to ohun ti Aluba le ke kuro.

Iba jẹ wipe gbogbo awọn ẹniti o nda ẹsẹ ti nwọn nhuwa bi ẹnipe kosi iku tabi ọjọ *Aliqiyaomat* ni arun yi nna ni paṣan ese wọn nko? A ko gbe ero kero si ẹnikẹni ṣugbọn a ya bara ba awọn ẹlomiran ti nwọn nṣe bi ẹnipe Iku Alumutu tabi ti nwọn ti ri wosika gba lati Sanma pe nwọn ki yio ku lailai.

Nitoripe pupọ enia li o npe ararẹ ni ọmọ-ẹhin Mọmọdu tabi Isa Jesu ti nwọn nka Bibeli ati Alukuran nigbagbogbo, ti nwọn si ngbọ wasu ọrọ ni Ṣọṣi ati ni Mọṣalaṣi, ṣugbọn ti nwọn nṣe eti kunkun si ọrọ Mọmọdu ati ti Kristi na.

Ni papa awọn ara ilẹ yi gbanran, nwọn ha nbikita si irufẹ ọran tamu-tamu ti o de'lẹ yi? Ani nwọn ha pa ti rogbodiyan ti o nbẹ larin wọn ti si apakan ki nwọn si kọ'bi ara si i? Pẹlu bi a ti ngba ara ta yi, nwọn ba mọ ni ọran wajibi bi? Iwa adonkiya ẹniti o ba lo kan kọ ni ero wọn, bibẹ kọ ẹ ha ṣe ti nwọn ko ṣe ipade kan ni gbangba bi iru Ita Balogun tabi ni ibomiran ki nwọn si ṣe ṣawura ti o yẹ lati ṣe ki Kiriyo wa nibẹ, ki Imale wa nibẹ ki awọn Abọriṣa si jọ pẹlu ki nwọn mọ ohun ti nwọn le ṣe lọna etutu ti olukuluku.

Nigba wo li eyi yio ri bẹ? Ati pe tani dide nisisiyi pe on yio pe lagbaja ati tamẹdo nipa Aluba na ki a si ri ẹniti o le sọ wipe ọran ija kọ ni eyi ọran ti o ba olukuluku ni, ki nwọn si ṣe ṣawura pataki ki nwọn si ko lọ ba awọn Munisiba tabi awọn Alakoso ilu—Bi eyi ba ri bẹ bawo ni ko tiṣe ni dara? Tani ko mọ wipe Ajakalẹ-arun ki iṣe on ti a le fi ọwọ kofo mu bikoṣe lọna ti adura tabi etutu; Alukọngọ a fi ọran na kọ nyin lọrun o.

Emi ni ti nyin nitotọ,

KEKERE-AWO.

---


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

***EKO AKETE***

EKO, SATURDAY, JULY 21, 1928.

## PRINCE EṢUGBAYI ELEKO ẸNI ỌTA MBUKU T'ỌLỌRUN MBUKUN.

Jijare ti Eleko jare ẹjọ rẹ ni Kotu Abẹṣẹ Ọba King ni Ilu Oyinbo tubo jẹ ki iferan to'nile t'alejo nibi gbogbo ni ilẹ *Nigeria* nisiyi di mimọ fun Ijọba, kosi si ẹniti yio ri ẹgbagbeje awọn enia ti nwọn nho iho ayọ kakiri nigboro Eko lẹnu ọsẹ kẹrin ọhun ti ki yio gbagbẹ pe lotọlotọ ifẹ ilu si Ẹni gbogoo aiye nfẹ na jẹ ifẹ gbigbona ; ifẹ ti ki ku.

Lẹnu ọdun kẹjọ sẹhin bawo ni Iwe Irohin ọsọsẹ kan ni igboro ilẹ yi ko ti yọ ṣuti si to, Iwe-irohin na ko sọ titi ko sọpe itumọ Eleko ti Ọba wa na njẹ koju pe nigbati o ṣi nṣe apẹja, nigbakugba ni o ma nri ẹja pupọ pa ju awọn alawo ẹgbẹ rẹ lọ: Iwe-irohin na sọ bayi lati fi bu atẹ lu Ẹni wa na. Ki a tilẹ sọpe otitọ ni itumọ orukọ na eyiti a ko jẹ gba ni iṣẹju kan pe bẹni. a ṣebi lẹhin igbati a ti pe ki o wa ṣe Olori wa nipa iirọpo ẹgbọn rẹ ni gbogbo wa ti fi ọkan kan duroti tobẹ ti diduroti bayi jẹ ohun iyanu fun awọn ko jẹ ki tẹnisuwọn miran, bẹni tẹnimasuwọn ki gbọ : a fi bi ilẹ kan ko mọ ni awọn Agba totorolọ ko ni gburo rẹ bi o ti wa ni alafia si ni Ode Ọyọ. Melo ninu ogunlọgọ ati ẹgbagbeje awọn enia ti nwọn gburo rẹ lo mọ ọ sọju? Alaimọ sọju ko sọ pe ki ifẹ wọn si ki o dinku nitoripe niwọn igbati gbogbo wa ti fi ọkan kan gba ni Ọba wa niwọn igbana si ni ifẹ olukuluku wa ti fi idimulẹ bi igbati aba iba ta egbo ti o si fi di mulẹ: ti Eleko ko le ṣe ki o ma ri bayi nitoripe ko si li abẹ ẹ bẹ joye kan ninu orọ tirẹ, ori oye ọtọ, bi awọn kan fi ekun kaka fi ara wọn si ọna oye jijẹ ọtọ. Bi Ijọba ba tilẹ tu bọ fẹ mọ bawo ni ifẹ Eko si Eleko ti tobi to ki Ijọba da gbogbo ilu Eko, Ebute Meta, ati Apapa si ẹna mẹwa nwọn yio ri pe ida mẹsan-abọ ni yio jẹ ti Eleko lai si tabitabi tabi abusọ nibẹ ;

Titi di bi a ti nkọwe yi ni gbogbo wa nreti pipada bọwale rẹ eyiti a tanma pe ko ni pẹ lọ titi mọ: lati igbati Prince Eleko ti jare ẹjọ rẹ na ni awọn kan ti nda idagiri pe "Wo, Eleko mbọ lọna" "A Eleko tide" eyiyi fi han pe kosi igbati ilu yio gbọ pe o mbọ lọna ti a ko ni si awọn ẹlomiran ti yio tile tọna lọ ko lọna lati Ode Ọyọ tabi ti ki yio ṣigbo lọ si Ọyọ lati ma ba Ẹni wa na bọ; bawo ni ẹṣẹ awọn *Boys* ko ti dun ilẹ to nigbati Ijọba nwa lọ ilọdun kẹta ọhun: ã ṣebi ojiji ni wiwa lọ rẹ na mu dani lọsan ganrin ganrin ni akoko igbati awọn oṣiṣẹ nṣiwọ bọ lọ sile papa awọn oniṣẹ ni Ebute Meta, sibẹsibẹ a ko ṣai ri ọgọrọ awọn *Boys* ti nwọn sin de Agege tabi jubẹlọ; ẹnu ko tun le ma sọ bi ero yio ti ma wọ nigbati o ba mpada bọ wa le: isọkusọ ti awọn ẹlomiran nsọ pe pipadade le yio mu ijaigboro dani ko le ṣai pa Ijọba lẹrin, melo ni ija igboro ti o ja gidi nigbati awọn Alagbara fi nfi ipa wa lọ nijọkini?

Dajudaju bi awọn ọta rẹ ti pe yio ri ko ri bẹ mọ eyi lo nmu awọn ẹlomiran lati ma so ohun ti kosi.

Talo le da Idajọ Are ti Kotu Abẹṣẹ Ọba King da Prince Eleko gbero njẹ bi Erin fẹ danwo iwo rẹ ki yio lọ baun? Adura ti a le ma gba ni pe ki dide rẹ ki o ma ṣai ṣoju olukuluku ni atari anfani.

Ẹda nlulu ibajẹ

Ọlọrun Ọba ko ni jẹ ki o dun!!!

---

## Thanks for Sympathy.

**Mrs. Isaac B. Thomas hereby returns her sincere thanks to all those who either by personal calls, letters or otherwise have extended sympathy with her on the occasion of the death of her husband on the 7th ultimo.**

## JAMAT EKO ATI MỌŞALAŞI.

Oniwe-'rohin yi jọwọ bun mi ni aye kekere kan lati fi ọrọ diẹ yi sinu iwe rẹ iyebiye na, eyiti o jẹmọ awọn Jamat Musulumu Eko ati Mọşalaşi, nipa abuku ti nwọn nfun Ile-Ọlọrun (Masjid) wọn ti o si kun fun iwa eri loju ti awa.

A ti ma nşe akiyesi awọn Jamat wọnyi ninu Mọşalaşi gbogbo ti o mbẹ ni arin ilu yi, iwa abuku ti a sọ wipe nwọn nsaba fi nlọ Mọşalaşi ni wipe ti nwọn ba mbẹ ninu rẹ lati şe isin tabi lati ki Irun (Salat) ọpọlọpọ wọn fẹran lati ma sọrọ ainilari ninu Mọşalaşi.

Lọna kini ki a ma sọrọ ainilari ninu Mọşalaşi nwọn fi nba aniyan tabi Irun awọn ẹlomiran jẹ lọna keji Ọlọrun papa şe ikilọ eyi pe a ni lati fun ibiti a ba npe orukọ On ni Ọwọ (*Respects*) ati irẹlẹ (*humbles*) a ko gbọdọ huwa eri si I, bẹni a ko gbọdọ sọ ọrọ ainilari ni işẹju kan ninu rẹ.

Lẹhinna awọn ẹlomiran si ma nki arawọn ninu Mọşalaşi, lẹhin igbati o jẹ wipe a şe Mọşalaşi lati ma sujada fun Ọlọrun, o ha yẹ wipe ki a tun ma sujada fun arawa ninu rẹ? Iwa mejeji yi awọn Jamat Musulumi ilẹ yi fẹran lati ma hu u-pupọ loju wa, iwa abuku ati iwa alaironu lo jẹ papa fun ẹniti o ba jẹ Musulumi papa.

Irufẹ iwa bayi jinna si awọn Jamat Ahmadiyya pupọ, awọn Jamat ti ọpọlọpọ awọn Imale ilẹ yi npe ni Jamat ti ko tọ suna.

Ọro pupọ ni a fẹ sọ loni lori ọrẹ nla yi, şugbọn a fẹ fi eyi şe ikilọ na fun gbogbo awọn ẹniti o huwa mejeji ti a ka yi; a si ke si Lemọmu—ilu Mọmọdu Ligali, ki o pe awọn Lemọmu Rabiti jọ ki o fi ọrọ yi si iwaju nwọn, ki olukuluku wọn le şe ikilọ yi fun awọn Jamat wọn ni Mọşalaşi ti olukuluku nki Irun.

MUSULUMI—ODODỌ.

## ORI IV.

## IŞẸ.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*).

APA KẸFA.

Bayi ni a ri i pe ki ọwọ ina dilẹ ni şişe işẹ ti o tọ jẹ nkan rere, ki işe fun ara nikan şugbọn fun ọkan pẹlu. Nibiti ọlẹ enia fi gbogbo ọjọ aiye rẹ şe imẹlẹ, ti gbogbo ire ti o wa lara rẹ sun lọ fọn-fon tabi ti o tilẹ di oku patapata, alakanloju enia a jẹ orisun işẹ ati igbadun fun gbogbo awọn ti o ba wa ni sakani rẹ.

Ani, işẹ-kişẹ (işẹ ti ko niyi) san şa ọgbanraye. Fuller sọ nipa Sir. Francis Drake, ẹniti o ti kekere lọ şe işẹ ninu ọkọ ti ọga rẹ si mu kọju mọ işẹ, pe "ifarabalẹ ati suru nigbati o wa ni ọmọde mu ọkan rẹ şe giri."

Schiller ma nsọ pe on ro pe anfani nlanla ni ki enia ni işẹ kan ti o nşe lojojumọ işẹ kana ti a ko gbọdọ şe aişe.

"Ọkẹ-mẹwa" enia a gba pe otọ ni ọrọ ti Greuze, onişọna ara France sọ pe, işẹ-işẹ şişe, işẹ ti o tọ-jẹ ọkan ninu awọn ọna aşiri pataki fun igbadun ara ẹni.

Ni ọjọ kan awọn ọrẹ Casaubon rọ ki o gba isimi fun ọjọ melo kan, ki o ma şe işẹ kankan; o gba, şugbọn o pada sibi işẹ rẹ, o ni o rọrun lati fi ara da amodi bi enia ba ri ohun fi ọwọ pa ju ki o ma rikan şe lọ.

